# NADABU ATI ABIHU

## Lefitiku 10:1-20; Numeri 3:1-4

## ẸKỌ 85 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ ma sìn OLUWA ninu ẹwà ìwa-mimọ́: ẹ wariri niwaju rẹ̀, gbogbo aiye" (Orin Dafidi 96:9).**

**Ayọ̀ Awọn Ọmọ Israẹli**

Ayọ̀ nlá nlà ni o wà ni ibudo awọn Ọmọ Israẹli ni ọjọ ti a ya Agọ si mimọ́, ti a si ya awọn alufaa sọtọ fun iṣẹ-isin mimọ́. Bawo ni inu awọn eniyan wọnyii ti dùn to lati tẹle aṣẹ Ọlọrun fun awọn irubọ naa! Nigba ti iná si bọ́ lojiji sori pẹpẹ, ti o si jó ẹbọ naa, ayọ̀ wọn kún akunwọsilẹ. Wọn mọ̀ pe lati ọdọ Ọlọrun ni iná yii ti wá, wọn si yọ̀ gidigidi pe O wà pẹlu wọn. Inu wọn dun to bẹẹ ti wọn doju bolẹ lati sin Oluwa.

Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ ri ibukun ti o tobi ju ti awọn eniyan iyoku lọ gbà. A yà wọn sọtọ fun iṣẹ-isin ninu Ibi Mimọ́. A wọ̀ wọ́n laṣọ ẹyẹ, eyi ti o wà fun awọn alufaa nikan, gbogbo eniyan si ri pe eniyan mimọ́ ni wọn. Ṣiwaju si i, Ọlọrun yan Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ meji, Nadabu ati Abihu, lati gun ori oke pẹlu Mose ati Aarọni ni akoko ti Ọlọrun fi ara Rẹ̀ han awọn aadọrin agbaagba (Ẹksodu 24:9-11).

Sa fi oju inu wo iru anfaani iyanu eyi ti wọn ni, lati sun mọ Ọlọrun to bayii! I ba ti mu inu wọn dun, ki o si mu wọn rẹ ara wọn silẹ to bẹẹ ti awọn i ba ti gbiyanju gidigidi lati wu Oluwa ninu gbogbo iṣẹ wọn. Ro ogo ti wọn i ba ti ni nikẹyin igbesi-ayé wọn, bi o ba jẹ pe wọn sin Ọlọrun tọkantọkan!

**Mimọọmọ Ṣaigbọran**

Ṣugbọn dipo ki Nadabu ati Abihu gbọran si Ọlọrun laaarin ayọ̀ ati ogo iyasimimọ́ yii, wọn ṣe aigbọràn, wọn si fi iná ajeji sinu awo turari wọn. Wọn kò ni awawi kan. Ọlọrun ti dá iná mimọ́ sori pẹpẹ, O si ti pese ohun gbogbo ti wọn fẹ fun iṣẹ-isin wọn. O ti fi pẹlẹpẹlẹ sọ fun wọn ohun gbogbo ti wọn ni lati ṣe. O si ti kilọ fun wọn pe wọn kò gbọdọ lo iná miiran ninu Agọ. Sibẹ lọjọ naa gan an ti O sọ fun wọn, ni wọn ṣe aigbọran. Wọn ro pe ọna ti wọn paapaa dara bẹẹ. Njẹ o mọ ohun ti o ṣẹlẹ si wọn?

**A Lù Wọ́n Pa**

Iná lati ọdọ Ọlọrun wá lu Nadabu ati Abihu, wọn si kú lẹsẹkẹsẹ, gẹgẹ bi kikọ manamana. Iṣẹju kan, wọn wá laaye – ni iṣẹju keji wọn di okú. Ọlọrun ti ṣeleri pe awọn ọmọ wọn yoo jẹ alufaa lẹyin wọn; ṣugbọn nitori aigbọran wọn, wọn ku ki wọn to ni ọmọ ti yoo rọpo wọn.

Ọlọrun n fẹ ki awọn eniyan gbọran si gbogbo aṣẹ Rẹ̀; nigba ti wọn ba si kọ̀ lati ṣe bẹẹ, idajọ Rẹ̀ yoo wá sori wọn. Alaanu ni, Oun ki i si fi igba gbogbo lu ẹlẹṣẹ pa lẹsẹkẹsẹ (bi o tilẹ jẹ pe eyi naa n ṣẹlẹ nigba miiran), ṣugbọn o daju pe idajọ n bọ̀. "Ọkàn ti o bá ṣẹ̀, on o kú' (Esekiẹli 18:4). Ọpọ ni kò gba eyi gbọ́, wọn si ro pe awọn yoo lọ si Ọrun bi wọn ba tilẹ dẹṣẹ. Adamu paapaa kò gbà eyi gbọ́, nigba ti o ṣaigbọran si Ọlọrun ninu Ọgbà. Ọlọrun ti sọ fun un pe bi o ba jẹ ninu igi imọ rere ati buburu, kikú ni oun yoo kú. Sibẹ, Satani sọ fun Efa pe wọn ki yoo kú, ṣugbọn wọn yoo dabi Ọlọrun. Bayii ni Adamu ati Efa gba eṣu gbọ́ ju Ọlọrun lọ. Bawo ni wọn ti jiya to! Wọn kú ikú ti ẹmi, Ọlọrun kò si tun ba wọn rin mọ́ ni itura ọjọ ninu Ọgbà daradara ni. O paṣẹ fun wọn lati fi Ọgbà nì silẹ, ki wọn si lọ sinu ayé ti o ṣe ajeji fun wọn, ki wọn si maa ṣiṣẹ karakara fun ounjẹ oojọ wọn. Wọn ni aisan ati irora, eyi ti ki ba ti de ba wọn bi o ba ṣe pe wọn ti gbọran si Ọlọrun lẹnu.

**Idajọ Daju**

Ọlọrun maa n mú suuru pupọ fun awọn ti kò mọ bi a ti n sin In, O si maa n fun wọn ni anfaani pupọ lati ronupiwada. Ṣugbọn aanu Rẹ̀ ki i duro pẹ́ nigba ti awọn eniyan ba mọọmọ ṣaigbọran si aṣẹ Rẹ̀. Nadabu ati Abihu ti sun mọ Ọlọrun to bẹẹ ti wọn mọ ifẹ Rẹ̀, o si yẹ ki wọn bẹru lati ṣe aigbọran si I. Wọn yẹ si idajọ ti Ọlọrun mu wá sori wọn lojiji. Wọn kò ni anfaani lati beere fun idariji.

**Ọrọ Ọlọrun Daju**

Ẹ jẹ ki a rò bi o ti ṣe pataki to lati gbọran si aṣẹ Ọlọrun. A ni Bibeli, Ọrọ Mimọ́ Rẹ̀, ninu rẹ̀ ni a si n ri ọna si iye ainipẹkun. Ọlọrun maa n fun ni ni aṣẹ Rẹ̀ ni ọna ti o le fi yé ni daradara. O wi pe "Awọn èro ọ̀na na, bi nwọn tilẹ jẹ òpe, nwọn kì yio ṣì i" (Isaiah 35:8). Nigba pupọ ni a maa n ri awọn ọmọ kekeke ti wọn ni oye bi a ṣe le ni igbala, ṣaaju awọn obi wọn. Jesu wi pe, "Bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si dabi awọn ọmọ kekere, ẹnyin ki yio le wọle ijọba ọrun" (Matteu 18:3). Awọn eniyan gbọdọ gbagbe èrò ti wọn, ki wọn si gbọran si Jesu lẹnu, bi wọn ba fẹ ri igbala.

Ninu Bibeli, a ri akọsilẹ itan igbesi-aye awọn eniyan nlá -- iṣẹ rere wọn ati iṣẹ buburu wọn. A ni akọsilẹ itan awọn orilẹ-ède ninu iwe mimọ́ yii pẹlu. Jesu wi pe a fi wọn fun wa gẹgẹ bi apẹẹrẹ. Nitori naa ni a ṣe gbọdọ maa ka Bibeli, ki a si maa ṣe aṣaro ninu rẹ̀, ki awọn apẹẹrẹ yii ba le jẹ́ ẹ̀kọ́ fun wa.

Bi awọn eniyan ti o wà ni ipo giga bẹẹ ba dẹṣẹ, gẹgẹ bi Nadabu ati Abihu ti ṣe ti a si pa wọn run nitori ẹ̀ṣẹ wọn a le ri i pe Ọlọrun yoo pa ẹnikẹni ti o ba dẹṣẹ run. Wiwọ aṣọ alufaa ati jijọsin ninu ile-isin kò le mu un wa ni imurasilẹ lati pade Jesu. Bi o ba dẹṣẹ oun yoo kú a o si jẹ ẹ niya. Jesu wi pe, "Ki iṣe gbogbo ẹniti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio wọle ijọba ọrun; bikoṣe ẹniti nṣẹ ifẹ Baba mi ti mbẹ li ọrun" (Matteu 7:21). Ni igba miiran, O wi pe, "Esitiṣe ti ẹnyin npè mi li Oluwa, Oluwa, ti ẹnyin kò si ṣe ohun ti mo wi?" (Luku 6:46). Ki ni ṣe ti a n pe ara wa ni

Onigbagbọ́ bi a kò bá n gbọran si gbogbo aṣẹ Ọlọrun? A ko ni de Ọrun bikoṣepe a ba gbé igbesi-ayé wa gẹgẹ bi gbogbo ọrọ ti Jesu ti pa laṣẹ fun wa.

**Ọlọrun Korira Isin Èké**

Awọn miran rò pe nitori wọn jẹ́ oloootọ ninu ẹsin wọn, nitori naa ko ja mọ nnkan ohunkohun ti wọn gbagbọ́. Njẹ ohun ti Bibeli kọ́ wa ni yii? Nadabu ati Abihu n sun turari ninu awo turari wọn gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun -- wọn n ṣe afarawe isin -- ṣugbọn wọ́n lo iná ajeji.

Ọlọrun korira isin èké. O sọ fun awọn Ọmọ Israẹli ni igba pupọ lati ṣọra lọdọ awọn ti n sin oriṣa; ki wọn si ri i pe wọn kò tẹle isin awọn keferi.

Ni igba kan nigba ti awọn Ọmọ Israẹli dẹṣẹ, Ọlọrun kò jẹ ki ojo rọ̀ sori ilẹ wọn fun ọdun mẹta ati aabọ. Ni opin akoko naa, Elijah pe awọn wolii Baali nija lati fi ẹni ti i ṣe Ọlọrun otitọ hàn. Ninu itara wọn lati ri idahun gbà lọdọ oriṣa wọn, awọn wolii Baali wọnyii fi ọbẹ ya ara wọn titi ẹjẹ fi tú jade. Ṣugbọn kò si idahun kankan. Wọn jẹ oloootọ ninu isin wọn, ṣugbọn ijolootọ wọn kò mú ere kan wá.

Jesu ti sọ fun wa pe, a gbọdọ sin baba ni "Ẹmi ati li otitọ". O tun wi pe, "Ẹ kiyesara, ki ẹ si mã ṣọra niti iwukara awọn Farisi ati ti awọn Sadusi" (Matteu 16:6). Ẹlẹsin ni wọn, ṣugbọn wọn ni ẹ̀ṣẹ ninu ọkàn wọn, nitori bẹẹ Jesu wi fun wọn pe eniyan buburu ni wọn. Lai ka bi wọn ti jẹ́ olufọkansin tó, ẹsin wọn ki i ṣe gẹgẹ bi ẹkọ Jesu.

Bawo ni i ba ti dara to bi awọn eniyan ba le mọ̀ pe yoo gba igbesi-ayé iwa mimọ́ ati aileeri, ati ọkàn ti a ti sọ di mimọ́ patapata eyi ti o mu wọn jẹ́ ọ̀kan pẹlu Jesu lati le mura wọn silẹ fun Ọrun! Eto isin pẹlu ọkàn ẹ̀ṣẹ kò le mura ẹnikẹni silẹ lati pade Jesu.

**Iná Ajeji**

Awọn ẹlẹsin miran naa n ni itara pupọ ati "iná" aṣerege, ṣugbọn "ajeji iná" ni eyi. Iru awọn eniyan bayii kò gbé igbesi-ayé wọn gẹgẹ bi Bibeli ti kọ́ ni. Jesu wi pe, "Eso wọn li ẹnyin o fi mọ̀ wọn" (Matteu 7:16). Nitori naa kò si bi eniyan ti le fi ara ṣe isin to, tabi ki o ni igbona ọkàn fun isin tó, bi oun kò ba n gbé igbesi-ayé mimọ́ ti o dara, eyi ti Jesu kọ́ ni, oun ki i ṣe Onigbagbọ́.

**Kò si Ibakẹdun fun Ẹṣẹ**

Lai ṣe aniani, Aarọni fẹran awọn ọmọ rẹ̀. O fẹran wọn pẹlu gẹgẹ bi ayanfẹ Ọlọrun. Ṣugbọn nigba ti Ọlọrun pa wọn run nitori ẹṣẹ wọn, Aarọni mọ̀ pe idajọ Ọlọrun jẹ́ otitọ, oun kò si ba wọn kẹ̀dun. Bi Aarọni ba ṣọfọ yoo dabi ẹni pe o n kùn si idajọ Ọlọrun ti o mú awọn alufaa buburu wọnyii kuro. Iṣẹ isin Ọlọrun ṣe pataki fun un ju ohun ti ara lọ. Oun ati awọn ọmọ rẹ̀ meji iyoku tẹsiwaju si i ninu iṣẹ-isin wọn.

Inu wa maa n bajẹ nigba ti ẹni kan bá fà sẹyin kuro lọdọ Ọlọrun, a o si maa gbadura kikankikan pe ki Ọlọrun ṣaanu fun un ki o si tun gba iru ẹni bẹẹ là. Ṣugbọn bi o ba kọ̀ lati wá Ọlọrun, a kò gbọdọ jẹ ki aigbọran rẹ̀ di wa lọwọ ninu isin wa fun Oluwa. Bi a ba ké ọkàn kan kuro nitori o ti sé ọkàn rẹ̀ le si Olugbala fun igba pipẹ́ a gbọdọ mu un kuro lọkàn wa, ki a si gbiyanju gidigidi lati jere awọn miiran sinu Ijọba Kristi.

Ọlọrun ran Wolii Samuẹli nigba kan lati yan Saulu gẹgẹ bi ọba Israẹli. Ọba titun yii jẹ́ onirẹlẹ ọdọmọkunrin kan ti o dagba ti o si di arẹwa ọkunrin; Samuẹli si fẹran rẹ̀. Nigba ti Saulu dagba si i, o gberaga, o si ṣaigbọran si Ọlọrun. Inu Ọlọrun bajẹ si Saulu to bẹẹ ti o fi kọ̀ ọ lọba. Eyi ba Samuẹli ninu jẹ́ pupọ. O ranti bi Saulu ti fẹran Ọlọrun tó nigba ti ó wà ni kekere, ó si ṣoro lati rò pé ó lè di eniyan buburu bayii. Ọlọrun sọ fun Samuẹli ni ọjọ kan pe, "Yio ti pẹ to ti iwọ o fi ma kãnu Saulu, nigbati o jẹ pe, mo ti kọ̀ ọ lati maa jọba lori Israẹli?' (1 Samuẹli 16:1). Ṣugbọn alaanu ni Ọlọrun, Oun kò si ni kọ ẹnikẹni ti o fẹ ri igbala.

**A fi Ogo fun Ọlọrun**

Ogo yoo jẹ́ ti Ọlọrun. Awọn alufaa ni anfaani lati maa gbé iwa mimọ́ Rẹ̀ ga nipa gbigbọran si I ninu irubọ wọn. Ṣugbọn dipo eyi Nadabu ati Abihu kò bu ọla fun Un. Nitori naa Ọlọrun fi iwa mimọ Rẹ̀ han awọn eniyan nipa pipa awọn ẹlẹṣẹ wọnyii run. Gbogbo eniyan ni o ṣọfọ awọn alufaa wọn ti a parun, wọn si mọ̀ pe wọn gbọdọ ṣọra gidigidi, ki awọn pẹlu, má ba dẹṣẹ ki wọn si gba idajọ Ọlọrun.

Ọlọrun ki i fi oju rere wo ẹ̀ṣẹ, nigba ti a ba si dá a ninu ile Ọlọrun gan an, o buru pupọ. Bawo ni eniyan ṣe le pe ara rẹ̀ ni Onigbagbọ́, ki o maa tẹle ilana isin, ki o maa ṣaigbọran si Ọlọrun sibẹ, ki o si maa mu ẹ̀gàn bá Ihinrere! A ba jẹ le mọ bi o ti ṣe pataki to lati pa ofin Ọlọrun mọ́ ki a si maa rin gẹgẹ bi ifẹ Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni Nadabu ati Abihu?
2. Nibo ni a ti gbọ́ nipa wọn tẹlẹ ri?
3. Bawo ni a ṣe n mu iná wá fun iṣẹ-isin inu agọ?
4. Ki ni aṣẹ Ọlọrun nipa iná naa?
5. Bawo ni o ti pẹ to lẹyin ti Ọlọrun pa aṣẹ yii ki Nadabu ati Abihu to ṣe aigbọran si i?
6. Ki ni ṣẹlẹ si wọn nitori aigbọran wọn?